The Bancroft Library

University of California · Berkeley

WILLIAM AND BERTA BASCOM
COLLECTION

A
R
S
ARS ADA
A
D
A

# I F A

# "O D U  M I M Ọ"

Awọn Aṣayan Odu Mimọ Ifa:  Akojọpọ kinni

lati inu

Ẹjiogbe, Ọyẹku-meji, Iwori-meji, Odi-meji,

pẹlu àlayé ati itúmọ̀ ọrọ

lati ọdọ

"ISỌWỌPỌ AWỌN AJỌ ẸLẸSIN IṢẸṢẸ ENIA DUDU (NAIJIRIA)"

[The Ancient Religious Societies of African Descendants Association]
(A.R.S.A.D.A)
[Incorporated in Nigeria]

Oloye Fagbemi Ajanaku Araba Eko.
Baba Ẹgbẹ Isọwọpọ Ajọ, ati
Alaga Igbimọ Akojọ Odu Ifa.

Ọgbẹni Laniyan Oduloju
Akọwe Igbimọ Akojọ Odu Ifa.

Ọgbẹni Abiọdun Baṣọrun,
Akọwe Isọwọpọ Ẹlẹsin Iṣẹṣẹ.

Ọgbẹni Fẹla Ṣowande
Olotu Iwe yi.

COPYRIGHT.

Gbogbo "Aṣẹ Iwe Yi"
wà lọwọ Isọwọpọ.

June 1965.

## AKỌLE

O jẹ nkan ayọ ṅidigidi fun mi lati ri i wipo Akojọ Odu Ifa yi de ibiti o de yi, pe awọn akojọ Odu Ifa lati inu awọn Ejiogbo, Ọyẹku-meji, Iwori-meji, ati Odi-meji, y nju de ibiti a lo mu wọn jade bayi na. Tí-tẹ awọn Odu wọnyi si inu Iwe tita fun gbogbo enia lati rí i lo gì wà ni iwaju. Ṣugbọn à-ti-tẹ iwe jade ki nya bọrọ; enia gbọdọ ni suru ti ki ntan ni. Fun igbayi, a gì lo mu u jade bayi na, eyi si yẹ ki o jẹ igiri fun gbogbo awọn ti o ti nṣe wahala lori akojọ wọnyi. Ifilọ pataki kan wá wà: ọnikọni ti o ba ri à-gì-kọ ni ibikankan ninu Iwe yi, ki o jọwọ jẹ ki a mọ, ki a ba le ṣe atunṣe, ki o to di wipe iwe nã jade ni titẹ.

Ẹnu mi ko gba ọpẹ ti mo gbọdọ da fun Isọwọpọ Awọn Ajẹ Ẹlẹsin Iṣẹṣe Enia Dudu (ti Naijiria), fun awọn ọmọ Isọwọpọ yi ti o wa ninu Igbimọ Akojọ Odu Ifa, ati pãpã fun Baba Ẹgbẹ ati Alaga Igbimọ: Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba Eko, fun gbogbo wahala ti nwọn ṣe lori Akojọpọ yi. Mo ni ireti wipe Iwe yi yio tubọ fun wọn ni igiri, ati wipe yio si fi han gbogbo wa wipe ore wà ninu ki a kọ Ifa si inu Iwe. Aiye ìwe ti de ilu wa, ọna ti jin. Eyini ni, aiye iwe-kí-kọ. Inu mi si dun lati ri i wipe Igbimọ Akojọ Odu Ifa yi ri i bẹ. Nitoripe, bi nwọn rí i bẹ, bi nwọn kò ri i bẹ, ko dá awọn ti o mura tan lati kọ ikọkukọ si inu iwe fun tita nipa nkan ibilẹ Yoruba duro, ati enia dudu, ati alawọ-funfun. Nitorina, aṣẹ ti Isọwọpọ Awọn Ajẹ Ẹlẹsin Iṣẹṣe Enia Dudu fi le Akojọ Odu Ifa wọnyi, jẹ nkan pataki, l'oḡu ni.

Ọlọrun yio jẹ ki a-ṣe-pọ wa yọri si rere; a kò ni ri itiju nibẹ o; a-ṣe-yọri ni yio jẹ, fun sí-se-awa Yoruba pọ ṣẹṣẹbi Orilẹ Ede kan ni abẹ Àṣẹ Ọlọrun Olodumare, Ẹleda Ọrun on Aiye, ati fun idagbasoke ninu Ìmọ Ọlọrun ṣẹṣẹbi o ti fi ara hàn fun wa, ninu igbesi aiye awọn Woli Rẹ Mimọ, pãpã Ọkunrin Dudu Oko Ìṣẹtí, Ọrunmila, Bara Agbọnnirogun.

Ọgbọni Fọlá Ṣowande,
Olotu Iwe yi.
Unifasiti Ibadan
June 1965.